# Ìrántí Alàgbà Fálétí (Àjíǹde Ẹlẹ́gbára)

Olayinka Agbetuyi
Thames Valley University
Reading
United Kingdom
yagbetuyi@hotmail.com

Adébáyọ̀, baba mi o!
Ọ̀tọ̀kùlú, Fálétí ni, ọkùnrin ogun
Adébáyọ̀, baba mi o!
Agùntáṣọọ́lò mi ọkùnrin ogun
Adébáyọ̀, baba mi o!
Bọ́bajírọ̀rọ̀ lóde Ọ̀yọ́ ọkùnrin orin
Adébáyọ̀, baba mi o!
Bọ́bagúnwà lóde Ọ̀yọ́ ọkùnrin orin
Ọ̀tọ̀kùlú akéwì Ọba Ọ̀yọ́ Aláàfin
Adébáyọ̀, baba mi o!
Ìmùlẹ̀ Àwíṣẹ Wándé Abímbọ́lá baba awo
Adébáyọ̀, baba mi o!
Òjíṣẹ gbédègbẹyọ̀, ẹlẹ́gbárá ọkùnrin orin
Adébáyọ̀, baba mi o!
Ẹbọra tó ń pèdè tonílé, tàlejò, tará oko
Adébáyọ̀, baba mi o!
Ọ̀tọ̀kùlú wo gómìnà lójú tìigi
Ó ní, a mẹni a jù, a mẹni ó jùwá lọ.
Adébáyọ̀, baba mi o!
Ọkùnrun tí a fi ń ṣépè ọkùnrin
Adébáyọ̀, baba mi o!
Kìnìún olóólà lórita Baṣọ̀run
Adébáyọ̀, baba mi o!
Òpó múlé ró, atófaratì bí òkè
Adébáyọ̀, baba mi o!

Ọ̀rọ̀ godo gànyìn òjíṣẹ́ẹ gbédègbẹyọ̀ ẹlẹ́gbárá
Adébáyọ̀, baba mi o!
Ó dàrìnnàkò, ó dojú àlá, ó dìgbòóṣe.
Ikú mẹ́ni ire lọ!
Adébáyọ̀, baba mi òòò!

